Sausage tree	pá-ń-dọ̀rọ̀	pá-ń-dọ̀rọ̀
A lime	òro-m̀-bó	òro-ṅ-bó
I am coming	mò ḿ bọ̀	mò ḿ bọ̀
I was sleeping	Mò ń sùn	mò ń sùn
I was giving him money	mò ń fi fún un lówó	mò ń fi fún un lówó
I am going	mò ń lọ	mò ń lọ
Askew	ìbú-m̀-bú	ìbú-ṅ-bú
Praying mantis	alá-m̀-paara	alá-ṅ-paara [alá-ŋm̀-paara] (whistle)
Thumb	àtà-m̀-pààkò	àtà-ṅ-pààkò [-ŋm-]
Something	n-ṅ-kan	n-ṅ-kan (whistle)
I shall come	n ó ˋwá	n ó ˋwá [ŋ]
or =	n ń ˋwá	n ń ˋwá
I did not come	n kò wá	n kò wá
or =	n ò wá	n ò wá [ŋ]
or =	n ṅ wá	n ṅ wá
He said he was coming	ó lóˋun ḿ bọ̀ [note the assimilated low tone.]	ó lóˋun ḿ bọ̀
Food	o-ń-jọ	o-ń-jọ (oúnjọ is also heard)
I don't go to Ibadan	n kì ń lọ sí Ìbàdàn	n kì ń lọ sí Ìbàdàn
Who called me?	ta ḿ pè mí.	ta ḿ pè mí [ŋm] from ta ni ó pè mí (see p. 44.)
Some personal names:	Bí-ñ-délé	Bá-ñ-délé
	Bá-ñ-kọ́lé	Bá-ñ-kọ́lé
	Bá-ñ-dúró	Bá-ñ-dúró
	Bá-ñ-jókòó	Bá-ñ-jókòó
	Olú-ñ-ládé	Olú-ñ-ládé
	Ṣóyí-ñ-ká	Ṣóyí-ñ-ká
	Láyí-ñ-ká	Láyí-ñ-ká
	Láfi-ń-hàn	Láfi-ń-hàn [ŋ](from ọlá ˋ fi mí hàn 'Honour revealed me)

LESSON XVI

Tone exercises

In the following, we are give the pronunciations of several sentences showing tone combinations that result in tone shifts of various kinds. First the future tense of a high-tone verb and a low-tone verb with pronoun objects.

	Olúwọlé	Àwùjọlá	
I will see you	èmi ó rí ọ̄ or èmi ó rí ọ̀	èmi ó rí ọ̄	[N.B.: The è- is an isolated low tone at the beginning of a phrase and is realized as a lowered mid: ē. It is actually a bit higher than the ọ̄ at the end. The ri is a tone-compromise form for rìí, which is also possible]

[In these exercises, a closer tone transcription is used than is necessary - or even correct - in ordinary writing]

you will see me	ìwọ ó rìí mī	ìwọ ó ri mī
he will see her	ōun ó rīī	ōun ó rīī
you will see us	īwọ ó rìí wā	īwọ ó rìí wā
I will see you (pl)	ēmi ó rīī yin	ēmi ó rīì yīn
you will see them	īwọ ó rii wọ̄n	īwọ ó ri wọ̄n
I will see you	ēmi ó ri ọ̄	ēmi ó ri ọ̄
you will see me	īwọ ó ri mī	īwọ ó ri mī

Now we will use a different verb, wò, to look at.

			(tonemically)
I will look at you	ēmi ó wóò ò ọ̄	ēmi ó wōò ò ọ̄	/èmi ó wò ó/
You will look at me	īwọ ó wóò mìí	īwọ ó wōò mìī	/ìwọ ó wò mí/
You will look at her	īwọ ó wò ó	īwọ ó wōò ō	/ìwọ ó wò ó/)

Mid-tone and high-tone verbs have characteristic tone transformations when they have a pronoun object in the third person singular. Thus - ó rí i, "he saw it," may become ó rii and even ó ri. Similarly, ó ṣe ó. "he did it", may become ó ṣeé and ó ṣé. HH

The following forms and sets of forms show that when a high-tone precedes two or more low-tones, one of the low tones is raised and may be realized as a falling glide or even as a high tone, in rapid, emphatic speech. Such a phonemic low tone may be marked with an "x" to show that its phonetic realization is variable.

	Olúwọlé	Àwùjọọlá	
How do we say, "He opened the door?"	ó ṣílẹ̀̌kùn	ó ṣílẹ̀̌kùn	
	whistled [´´´´´]	ó ṣílẹ́ẹ̀̀kùn	[ṣí ilẹ̀kùn]
Now will you give me the name, "The king of Ibadan"?			
	OlúBa̋dàn	OlúBa̋dàn	[` ` ` ` `]
Goodbye, au revoir!	ó dáb̋ọ̀ o!	ó dáb̋ọ̀ o!	[di àbọ̀]
I went up	mo gòkè	mo gòkè	
You went up	o gòkè	o gòkè	
he went up	ó g̋òkè	ó g̋òkè	
we went up	a gòkè	a gòkè	
you (pl) went up	ẹ gòkè	ẹ gòkè	
they went up	wọ́n g̋òkè	wọ́n g̋òkè	

Now let's use the long pronouns.

I went up	èmí g̋òkè	èmí g̋òkè	
you went up	ìwọ́ g̋òkè	ìwọ́ g̋òkè	
he went up	òún g̋òkè	òún g̋òkè	
we went up	àwá g̋òkè	àwá g̋òkè	
you (pl) went up	ẹ̀yín g̋òkè	ẹ̀yín g̋òkè	
they went up	àwọ́n g̋òkè	àwọ́n g̋òkè	45

Note that yó, or yíó, future, and má, negative raise the first of two low tones, despite the low tone that follows both of these forms in other contexts.

	Olúwolé	Àwùjoolá	
He will go up	yíó gǒkè	yíó gǒkè	[yó]
He did not go up	kò gòkè	kò gòkè	
He will not go up	kò níí gǒkè	kò níí gǒkè	
the work of a person	isé ènìyàn	isé ènìyàn	
respect for the elders	olá àgbà	olá àgbà	
my mother's friend	òré ìyáà mi	òré ìyáà mi	
he has read	ó ti kàwé	ó ti kàwé	
he read	ó kàwé	ó kàwé	
tàbí	[ó kâwě]	[ó kâwě]	
don't read	má kàwé	má kàwé	
he will read the book	yíó kàwé	yíó kàwé	[kâwě]
he explained	ó túmò	ó túmò	
he did not explain	kò túmò	kò túmò	

When a low tone has been elided, it often leaves its effect on the next tone. It may be written in various ways: jáde̅, já.de, or já`de; yó.wá, yó `wá, or yó wàá, "he will come."

	Olúwolé	Àwùjoolá	
don't explain	má `túmò	máà túmò	
he will explain	yíó `túmò	yíó `túmò	
he took care of it	yíó `tójúu rè	yíó `tójúu rè	[perhaps tojú with a compromise mid-tone]
don't take care of it	má `tójúu rè	má `tójúu rè	
he didn't take care of it.	kò tójúu rè	kò tójúu rè	
you are taking care of it	ò ń tójúu rè	ò ń tójúu rè	
you will not take care of it	o kò níí tójúu rè	o kò níí tojúu rè	
he went out	ó já`de	ó já`de	He

he goes out tomorrow	ó ń jádē̱ lọ́la já`de	ó ń já`de lọ́la [í í jádē̱ lọlā̄]	[tonetically ó ń jádē̱ lọlā̄] (habitual - tomorrow is his regular day for going out)
he eats tomorrow, breaks his fast tomorrow	íí jọun lọ́la	íí jọun lọ́lā̄	[N.B. downdrift]
(whistle it please)			
he goes out tomorrow	í í já`de lọ́la	í í já`de lọ`la	(whistle)
Trade is what he did	òwò ló ṣe	òwò ló ṣe	
you traded	o ṣòwò	o ṣòwò	
I traded	mo ṣòwò	mo ṣòwò	
he will trade	yíó ṣ̌̄wò	yíó ṣ̌̄wò	
he traded	ó ṣ̌̄wò	ó ṣ̌̄wò	
don't trade	má ṣ̌̄wò	má ṣ̌̄wò	
he didn't trade	kò ṣòwò	kò ṣòwò	
he will trade	yíó ṣ̌̄wò	yíó ṣ̌̄wò	
he will not trade	kò níí ṣ̌̄wò	kò níí ṣ̌̄wò	
it is certain	ó dájú	ó dájú	
it is not certain	kò dájú	kò dájú	[N.B. up-glide on dá-, which may become compromise mid-tone]
it will be certain	yíó `dájú	yíó dàājú	[yíó dàajú]
it will not be certain	kò níí dájú	kò níí dájú	[kò nīī dájú]

Exercises on the words NI

Here we have a few sentences using the various words or verbs NI in Yoruba. Here we have 'ni' meaning "to be".

	Olúwolé	Àwùjoolá
she is my wife	ayaà mi ni	ayaà mi ni
tàbí	obìnrìin mi ni	obìnrìin mi ni

47 48

	Olúwọlé	Àwùjọọlá
tàbí	ìyàwóò mi ni	ìyàwóò mi ni
tàbí	ayaà mi ló jẹ́	ayaà mi ló jẹ́
tàbí	ayaà mi níí ṣe	ayaà mi níí ṣe
She is Àìná	Àìná ló jẹ́	Àìná ló jẹ́
Yes, thus it is	bẹ́ẹ̀ ni	bẹ́ẹ̀ ni
Is it so?	bẹ́ẹ̀ ni?	bẹ́ẹ̀ ni?
tàbí	bẹ́ẹ̀ ni bí?	bẹ́ẹ̀ ni bí?
I wonder if it is so	bẹ́ẹ̀ ha ni bí?	bẹ́ẹ̀ ha ni bí?
That is how matters stand	bẹ́ẹ̀ nìì	bẹ́ẹ̀ nìì
Is this his horse?	tirẹ̀ lẹṣiìn yi bí?	tirẹ̀ lẹṣiìn yi bí?
Is it his that this horse is?		[yi, tone-compromise for yìí or `yí]
Here it is	ọun nìyí	ọun nìyí
This is the one it is	ọun nìí	ọun nìí
You are our King	Èyin ni Ọbáa wa = Èyin lỌbaa wa	= Ọbaa wa lèyín ṣe.
He is our King	Ọbaa wa ló jẹ́	Ọbaa wa ló jẹ́
or	Ọbaa wa ní í ṣe	Ọbaa wa ní í ṣe
His father is this elderly man	Bàbáa rẹ̀ làgbàlagbà yí	Bàbáa rẹ̀ làgbàlagbà yí
Who is it	Ta ni?	Ta ni?
Who ate it?	Ta ló jẹ ọ́? =	Ta ní jẹ ọ́? = Ta ń jẹ ọ́?
Who called me?	Ta ń pè mí?	Ta ń pè mí?

Now, we have "kò níí", the future negative.

It is I who will not go	Èmi ni n kò níí lọ =	Èmi ni ǹ níí lọ - Èmi ni ùn níí lọ
He will not do it.	Kò níí ṣe é	Kò níí ṣe é

Now we have ní, "to own or possess", and ni, "to own a specific thing"

He is weak, has no strength.	Kò ní agbára. =	Kò lágbára [NB up-glide on lá]

	Olúwọlé	Àwùjọolá	
He is in good health	Ó ní`lera	Ó ní`lera	
tàbí	Ó níl̄er̄ā	[< ní ìlera, hence lowered mid tone]	
Who has a dog, any old dog?	Ta ló ní ajá? = Ta ló lájá? - Ta ní láj̀á? - Ta ń láj̀á?		
We have a corpse to bury	A ní òkúú sin. = A ló`kúú sin.		
I am the one who owns books, any old books, many books	Èmi ni mo ní`wé		
I am the one who owns the book	Èmi ni mo nìwé náà		[ni, "to own specific thing"]
Who owns this money?	Ta ní ni owó `yí = Ta ní lowó `yí		
=	Ta ló lowó `yí = Ta ń lowó `yí		
Who owns this dog?	Ta ń lajá `yí = Ta ní lajá `yí?		
=	Ta ló lajá `yí?		

Now we have the various uses of oní, the possessor of something, in which we see the initial vowel change to match the **second vowel.**

	Olúwọlé	Àwùjọolá	
Shoemaker	onísʰbʰàtà	onísʰbʰàtà	
seller of àkàrà	alákʰàrà	alákʰàrà	
married man	olóbìnrin	olóbìnrin	
person with a child	ọlọ́mọ	ọlọ́mọ	
another person's child	ọmọọlọ́mọ	ọmọọlọ́mọ	
A liar	elé`ké	elé`ké	[èké, a lie]
this one	elé`yí	elé`yí	
a witness	ọlọ́`rí	ọlọ́`rí	[ọ̀rí, evidence]
fishmonger	ọlọ́ja	ọlọ́ja	
a married woman	ọlọ́kọ	ọlọ́kọ	
a farmer	olóko	olóko	

Eni, 'person', usually loses its first vowel when it follows a verb, e.g.: apani, 'murderer' [a-pa-ọni]. But note kò sọ́ni tó leè ṣe é, 'there is no one who can do it.' Note also ọlòmíràn, 'somebody else' [< ọni òmíràn]. Compare aninilára, 'tyrant' below.

Now we have ní, "to say that" or "to tell".

	Olúwolé	Àwùjoolá
Tell him to come	ní kó wá	ní kó wá
He said that father has arrived	Ó ní bàbá ti dé.	Ó ní bàbá ti dé

They said that they (other people) did not wish to go. They said that the other people did not wish to go.

Wọ́n ní wọn ò fẹ́ lọ Wọ́n ní wọn ò fẹ́ lọ

They said that they (themselves) did not wish to go.

= Wọ́n láwọn ò fẹ́ lọ Wọ́n láwọn ò fẹ́ lọ

You didn't tell me to say it again.	E ò ní kí n tún sọ ọ́	E ò ní kí n tún sọ ọ́.
You didn't need me to say it again.	E ò tún ní pé kí n sọ mọ́	E ò tún ní pé kí n sọ mọ́. [ní pé, to need. (Enter in Abraham, ní C7)]
He said that she came	ó lé wá	ó lé wá
He said that he himself came	Ó lé'un wá	Ó lé'un wá
He said that she didn't come	Ó ní kò wá	Ó ní kò wá.
He said that he himself didn't come	Ó lé'un kò wá	Ó lé'un kò wá
What did he say?	Kí lé wí?	Kí lé wí?
He said that she came.	Ó lé wá	Ó lé wá

We have ni, to make uncomfortable.

I felt uncomfortable.	Ará ni mí	Ará ni mí
It makes me uneasy	Ó ni mí lára	Ó ni mí lára
Ease, or comfort	àìnira	àìnira
discomfort	ìnira	ìnira
A tyrant	aninilára	aninilára [a-ni ẹni ní ara]
Freedom	òmìnira	òmìnira [mì, 'shake' (?)]
Freetown, Sierra Leone	Ìlú Òmìnira	Ìlú Òmìnira

We now have the prepositional use of - ní.

	Olúwolé	Àwùjoolá
He is at home	ó wà nílé	ó wà nílé
They adopted each other as friends.	Wọ́n mú araawọn ní ọ̀rẹ́.	Wọ́n mú araawọn ní ọ̀rẹ́.
tàbí =	Wọ́n mú araawọn lọ́`rẹ́	Wọ́n mú araawọn lọ́`rẹ́
The local government in Ọyọ́	Ìjọba Ìbílẹ̀ Ọyọ́	Ìjọba Ìbílẹ̀ Ọyọ́
tàbí =	Ìjọba Ìbílẹ̀ lọ́`yọ́	Ìjọba Ìbílẹ̀ lọ́`yọ́.
He bought it for two shillings.	Ó rà á ní ṣílè méjì	Ó rà á ní ṣílè méjì
tàbí =	Ó rà á fún ṣílè méjì	Ó rà á fún ṣílè méjì
Come here!	Wá níbí!	Wá níbí!
tàbí =	Wá síbí!	Wá síbí!
tàbí =	Wá ní`hín	Wá ní`hín
tàbí =	Wá sí`hín	Wá sí`hín
He sent them there	Ó rán wọn níbẹ̀	Ó rán wọn síbẹ̀.

	Olúwọlé	Àwùjọọlá
Or I can say,	Ta lèmí í ṣe?	Ta lèmí í ṣe?
Who are you?	Ta ni ọ́?	Ta ni ọ́?
Who is he?	Ta lọun?	Ta lọun?
Who are we	Ta ni wá?	Ta ni wá?
Who are you (pl)	Ta ni yín?	Ta ni yín?
May I know, please to whom I am speaking?	Ẹ jọ̀ọ́, ta ni yín?	Ẹ jọ̀ọ́, ta ni yín?
Who are they?	Ta ni wọ́n?	Ta ni wọ́n?

When another verb follows, /ni/ becomes /ní/, from ni ó./

Who ate it?	Ta ní je ẹ́? =	Ta ń je ẹ́? = Ta ni ó je ẹ́?
Who equals God?	Ta ní tọ́lọ́run? =	Ta ni ó tó Ọlọ́run? = Ta ń tọ́lọ́run?
Who is a fool?	Ta ní í ṣe òmùgọ̀?	Ta ní í ṣe òmùgọ̀?

54

Iwé Ikíni àti Ijéni

Book of Greetings and Responses

by

R. L. Awùjọọlá

Ikínii Yorùbá	Yoruba Greetings	
Ikíni ojoojúmó	Daily greetings	(from dawn to fore-noon)
Ikíni lóàárò	Morning Wishes	

(Ikíni = greetings; Ijéni = response)

Specimen 1

Ikíni:	Ẹ káàárò o!	Good morning!
Ijéni:	Òo, ẹ káàárò náà!	Thank you! or Yes, good morning!

Specimen 2

Ikíni:	Ẹ kú ojúmó o!	Good morning!
Ijéni:	Òo, ẹ kú ojúmó náà!	Thank you, good morning!

Specimen 3

Ikíni:	Ẹ jíi re õ!	Good morning! ("Did you wake well?)
Ijéni:	Òo, ẹ kú ojúmó o.	Thank you, good morning.

Specimen 4

Ikíni:	Ẹ kú ìdájí o!	Good morning, very early!
Ijéni	Òo, ẹ kú ojúmó !	Thank you, good morning.

To follow any of the above:

Ikíni:	Ṣé àláfíà le jí?	I hope you woke in peace?
Ijéni:	Aláfíà ni, a dúpé.	In peace, thank you.
or Ikíni:	Ṣé daadaa le jí?	I hope you woke well?
Ijéni:	Daadaa ni, a dúpé.	Well it was, thank you.

To follow any of the four specimens:

Ikíni:	Ẹ ò jí bí?	Good morning! ("Did you not wake well?")
	= Ẹ ò jíi re bí? =	Ẹ ò jíi re bí?
Ijéni:	A jí o, a dúpé! =	A jíi, a dúpé! We did wake well, we are thankful!
or A jí o, a yinLọun!		We woke well, praise God! [yin/ọlọrun]

tàbí =	Wá sí`hín	Wá sí`hín	
He sent them there	Ó rán wọn níbẹ̀	Ó rán wọn síbẹ̀.	
He is rich.	Ó lówó lọ́wọ́	Ó lówó lọ́wọ́	
He has money in hand	Ó lówó lọ́wọ́	Ó lówó lọ́wọ́	
He is full of pranks mischievous.	Ó ní lọ́wọ́	Ó ní lọ́wọ́	
He gave me money.	Ó fún mi lówó.	Ó fún mi lówó.	
He gave me a yam.	Ó fún mi níṣu.	Ó fún mi níṣu	
He gave his child or his daughter in marriage.	Ó fún ọn lọ́mọ	Ó fún ọn lọ́mọ	[ọn < wọn]
He entrusted the money to me.	Ó fowó lé mi lọ́wọ́.	Ó fowó lé mi lọ́wọ́	[fi]

Now we have the phrase /ta ni/ meaning "who?"

Who is it?	Ta ni? =	Ta ni o̩?	
Is it I.	Èmi ni	Èmi ni.	
Is it he.	Òun ni.	Òun ni.	
Who am I?	Ta ni mí?	Ta ni mí?	
	(meaning, "Who am I?" or "I am of no importance")		

Ìkíni:	Ilé ńkọ́?	How is the family? (house)
or	or ~~[illegible]~~gbo ilé ńkọ́?	How is the whole family?
	or Awọn aráalé ńkọ́?	How are the members of the family (of the house?)
Ìjẹ́ni:	Ilé ḿ bẹ = ilé wà = ó wà, a dúpé!	The family is fine, thank you.
	or: Wọ́n ḿ bẹ, a yinLọ́un = Wọ́n wà, a yinLọ́un	They are fine, we praise God.

Specimen 5

Say this to the first person whom you chance to meet that morning. It is somewhat like the English.

1st person "Top of the morning to you!"

2nd person "The rest of the day to you!"

Ìkíni:	Ají rí o!	(You are the first person I shall see this new day and I greet you!) "Waking and seeing," or perhaps, "Waking in order to see."
Ìjẹ́ni:	Òo, òní á sàn yín o!	May this day be better, or more favourable, for or to you, (for your seeing me, first of all this morning)
Ìjẹ́ni 2:	Á kàn yín o!	A part of whatever good or fortune comes my way will be yours. ("It will reach you.")
Ìjẹ́ni 3:	Amín o, Ẹ ṣé o!	Amen, thank you! ("You have done it!")
Ìjẹ́ni 4:	Ilé ńkọ́? etc.	How is your family?
Ìjẹ́ni 5:	Ó ḿ bẹ, a dúpẹ́ = ḿ bẹ, a dúpẹ́.	Fine, we're thankful, etc.

Specimen 6 -- A complete wish

Ìkíni:	Ẹ káàárọ̀ o!	N.B. [káàárọ̀ọ̀ o] -- stressed onset of downglide
	or: Ẹ jíi re ō!	

Ìjẹ́ni 1: Ẹ kóojúmọ́ o! Ṣé daadaa lẹ jí?

Ìjẹ́ni 2: Daadaa ni, a yinLọ́un. Ilé ńkọ́?

Ìjẹ́ni 3: Ó wà, a dúpẹ́.

2. **Lósàn:** (Fore-noon to about 3 p.m., according to weather)

Ikíni:	Ẹ káàsán o!	Good day! or good afternoon [intonation A]
Ijẹ́ni:	Ọ̀o ṣé àlafíà lọ wà?	How are you?
Ijẹ́ni 2:	Àláfíà ni, a dúpẹ́.	Fine, thank you.
Ikíni:	Awọn aráalé ńkọ́?	
Ijẹ́ni:	Wọ́n ń bọ, a dúpẹ́.	
Ikíni:	Ó dábọ̀ o!	Goodbye! ("Until the return." Note the positionally conditioned high tone on dá-)
Ijẹ́ni:	Ọ̀o, ó dígbà.	("Until the time". N.B. positionally conditioned high tone on dí-)

3. **Ní Irọ̀lẹ́ tàbí Aṣálẹ́** (In the cool of the day, or the afternoon, from about 5 p.m. till sun-down.)

Ikíni:	Ẹ kú irọ̀lẹ́ o = ẹ kú àṣálẹ́ o!	Good afternoon! or good evening.
Ijẹ́ni:	Ẹ kú irọ̀lẹ́ náà = ẹ kú àṣálẹ́ náà. Ṣé dáadáa ni?	Thank you, good afternoon! How are you? ("greetihgs on the afternoon, with respect to the afternoon!)
Ijẹ́ni 2:	Daadaa ni! a dúpẹ́	Fine, thank you!

N.B. Ṣé daadaa ni? or Ṣé àláfíà ni? or Ṣé àláfíà lọ wà? are the same as "How do you do?" But instead of the English "How do you do?" response, we say "àláfíà ni" or "daadaa ni", according as "àláfíà" or "daadaa" is used in the wish.

4. **Lálẹ́** (in the evening, after sunset)

Ikíni:	Ẹ kú alẹ́ o - ẹ káalẹ́ o = ẹ kú ojú alẹ́ o!	Good evening.
Ijẹ́ni:	Ọ̀o, ẹ kú alẹ́ náà! etc.	
Ikíni:	Ṣé dáadáa ni or: ṣé dáadáa lọ wà? etc.	
Ijẹ́ni:	Daadaa ni, a dúpẹ́	

Ìkíni: Ilé ò daa bí?

or: Àláfíà kọ́lé? ("Isn't the family well?")

Ìjẹ́ni: Ó daa

or: Àláfíà nìì, a yinLọ́un

5. Kí á tó pínyà lálẹ́ (Before we part in the evening)

Ìkíni: Ó dàárọ̀ o!

= ó dòórọ̀ Good night! ("until morning")

= Ó dojúmọ́ o

= ó dojú ọ̀-mọ̀ ("till daylight").

Ìjẹ́ni: Òo, Olúwa ó ṣọ́ wa o! The Lord watch over us!

Ìjẹ́ni 2: Amín o!

Another Specimen

Ìkíni: Ó dòórọ̀ o!

Ìjẹ́ni: Òo, ká sùn̄ re ō! May we sleep well!

Ìjẹ́ni 2: Amín o! Ẹ kílé o! Greet (your) house, family.

Ìjẹ́ni 3: Ilé yíó `gbọ́. The family will hear.

Another Specimen

Ikíni: Ká sùn̄ re ō! May we sleep well!

Ìjẹ́ni: Amín o!

Ìkíni: Ọ̀la nílẹ̀ yó `mọ́ o! At daylight tomorrow it is then day will begin. (Tomorrow the earth will be bright)

Ìjẹ́ni: Amín o! Ká dóru kọjá o! May we live past the night (to see the light of another day.)

Ìjẹ́ni 2: Amín o! a ò níí fòru pàdé o! May we not have an occasion to force us to meet in the night (before dawn)! (E.g., because of sickness)

Ìjẹ́ni 3: Amín o! Ó dáàárọ̀ etc

Another Specimen

Before parting, say in the morning, with no hope of seeing again that day,--

Ìkíni: O di ọ̀la ō - ó dọ̀la ō! Until tomorrow!

Ìjẹ́ni: Òo, ó dáàárọ̀!

or: ó dijọ́ `míì Until another day!)

Note well!

At any time of the day, any of these wishes is appropriate:

Ṣé daadaa lẹ wà? = ṣé daadaa ni?

Ṣé àláfíà lẹ wà? = ṣe àláfíà ni?

Àláfíà kọ́ bí? = àláfíà kílé

Àláfíà kọ́lé? = àláfíàà?

Daadaa kọ́? = daadaa?

Ara ò le bí? = ṣé ará le? (Is body not strong? Hope body is strong?)

Response to the last, = Ará le, or ó le a dúpẹ́.

Each of the above is the same as "How do you do?"

II. Ìkíni ní Orísìírísìí Ìgbà

(Various Occasions)

6. To someone you have not seen for a long time (due to distance), or someone you don't see as often as you should, though not far off, following the appropriate greetings for that period of the day:

Ìkíni: Kò tójọ́ mẹ́ta? — Is it not up to three days (since I last saw you?) (I have not seen you for quite a time! Quite an age.) or: Ẹ kú ọjọ́ mẹ́ta! (I greet you on three days.)

Ìjẹ́ni: 'Jọ́ kaán pẹ̀lú! or, ọjọ mẹ́ta náà ni! — (The whole exchange is equivalent to "How are you?" "Fine!" "Three days" is a figure of speech, meaning "a long time.")

Ìjẹ́ni: Ẹ kú àtijọ́! — Greetings on several days ("from days") (Haven't seen you for a long time.)

= Òo, ẹ kúu láé-láé! — Greetings on the long time!

Ìkíni: Níbo lẹ ti lọ̀? — Where have you been? [emphatic drop to low tone]

Ìjẹ́ni: Ilé náà ni mo ti wà, n ò lọ ibì kan! N ò rebì kan! I have been at home all the while; I have not gone anywhere.

Ìkíni: Ǹjẹ́ a kò ríra ni? — Then, that means we simply have not seen each other.

Ìjẹ́ni: Bọ̀ọ̀ ni! Ó dígbà o! — Until another time [for dìgbà, after high tone]

10. Kíkí àwọn alárìsàn — Greeting the sick

As you approach a person's house, say:-

Ìkíni: Àgò, onílé o! — House-owner, I ask for admittance.

Ìjẹ́ni: Àgàò yà o! Ẹ wọlé o! — Admittance is granted, come right in! (If the door is locked):-

Ẹ jọ̀ọ́ à ń bọ̀ o. — We are coming, please. [The speaker actually says ...bọ o̅, using a compromise tone for the high-low glide.]

Ìkíni: (Member of the house)

Ẹ káàárọ̀ o. — Good morning [káàárọ o̅]

Ìjẹ́ni: Òo, ṣé ilé daa? — Thank you, is the family well?

Ìjẹ́ni 2: Daadaa ni a dúpẹ́, — Well, thank you.

Ìkíni: Ẹ wọlé. Ẹ wá jókòó níbí. Ẹ kúkàlẹ́! —

Ìjẹ́ni: A dúpẹ́. Òjó la fẹ́ rí. — It is Òjó whom we want to see.

Ìjẹ́ni 2: Òun nìyí. Àárẹ́ ń ṣe ẹ̀. — Here he is. He has been ill.

Ìkíni: Àà! Ó mà ṣe o̅! Ẹ pẹ̀lẹ́, Òjó! — Oh, it's a pity. We're sorry!

Ìjẹ́ni: Òo. (feebly)

Ìkíni: Ẹ pẹ̀lẹ́! Olúwa yíó mú àláfíà wá o! — I am sorry! The Lord will bring peace!

Ìjẹ́ni: Àmín o! Ẹ ṣe é. (weakly) — Thank you.

Ìkíni: Nígbàwo ni àmódi ti ń ṣe ó? — How long has he been ill?

Ìjẹ́ni: Àná ná ló bẹ̀rẹ̀̄. — Yesterday is when it started. [-rẹ̀̄, rise for emphasis]

Ìkíni: Irú àìsànwo nìí? — What kind of sickness is it?

Ìjẹ́ni: Ẹ̀fọ́rí àti inú rírun ni. — He has a headache and stomach-ache.

Ìkíni: Ẹ pẹ̀lẹ́! Olúwa yíó ṣe Onísègùn yín. — The Lord will be your physician.

Ìjẹ́ni: Àmín o! Ẹ ṣe é.

Ìkíni: Ẹ kú àájòo rẹ̀. — Greetings for your tender care of him.

Ìjẹ́ni: A dúpẹ́. A kú dìde. — Thank you for coming, calling.

Ìkíni: A tún maa rí ra o̅! A ò ní í pẹ́ wá wò yin. Ẹ múnra gírí! Olúwa yíó bukún rẹ rù. — We will be seeing each other again. We shall come and see you before long. Get up quickly. The Lord will lessen its effect.

Ijẹ́ni: Àmín o! Nígbàwo ló tún dà? — When shall it be again?

Ìjẹ́ni 2: Ẹ ó rí wa nírọ̀lẹ́ ọ̀la, bí kò bá sí nǹkankan. You'll see us tomorrow afternoon, if all is well.

Ìkíni: Ẹ ṣe é. A dúpẹ́. Ẹ kílé o! Ká fi re pàdé o! Thank you, thank you! Greet your family! May we meet in peace!

Ìjẹ́ni: Amín o! Ó dọ̀la ō. Until tomorrow!

Ìjẹ́ni: Òo, ẹ káàbọ̀. Thank you for coming.

11. Àwọn Èèyàn ní Ìdúró — People Standing

Ìkíni: Ẹ kú Ìdúró — Greetings to those standing!

= ẹ kúùdúró!

= ẹ kú Ìdáró

= ẹ kúùdáró!

Ìjẹ́ni: Oo, ẹ káàbọ̀ o! Thank you, Welcome! Tàbí (or)

Ìkíni: Ẹ kú àníyàn o! Greetings on (your) taking thought, taking counsel. (Said to a group in serious discussion, or to a single person deliberating.)

Ìjẹ́ni: Òo, ẹ ṣe é o!

or: Ẹ kú àpérò o! Greetings on your discussion! (Said to a group, sitting or standing in light or serious talk.)

Ìjẹ́ni: Òo, ẹ ṣé o!

12. Àwọn tí ń lọ sí Ìdálẹ̀ (Ìrin-àjò) — Those making a trip

Ìkíni: Ẹ kúùrìn o! Greetings on the journey!

or: ó dáàbọ̀ o.

Ìjẹ́ni: Òo, ó dábọ̀! Goodbye.

Ìkíni: Ẹ rè wá o! Goodbye ("You (will) go-come")

Ìjẹ́ni: Òo, o dábọ̀

Ìkíni: Olúwa yíó pa ọ̀nà mọ́ o. The Lord will preserve your way.

Ìjẹ́ni: Amín o! Ká fi re pàdé o. May we meet well.

Ìjẹ́ni 2: Amín o, dáadáa lẹ ó dé o! Amen, you will arrive well!

Ìjẹ́ni 3: Amín o.

13. Ẹ Káàbọ̀! Welcome!

Ìkíni: Báríkà! Báríkà! Ẹ kábọ̀ o! Welcome!

Ìjọ́ni: Ẹ kúulé o! Ṣé dáadáa la bálé? Greetings to the family. Hope we find the family well.

Ìjọ́ni: Daadaa nìì. Ẹ kúùrin. Ṣé dáadáa lọ dé? We are well. Greetings on your trip. Did you have a good trip? ("Have you arrived well?")

Ìjọ́ni: Ìrìn náà dùn, a dúpẹ́. It was a fine trip, thank you.

14. Ní ilé Oníyàwó At the House of one who has just got married

Ọ̀rẹ́ kinní, First friend. Ọ̀rẹ́ kejì Second Friend.

Ọ̀rẹ́ 1: Ọ̀rẹ́mi, kò tójọ́ mẹ́ta? My friend, is it not up to three days? (I have not seen you for a long time!)

Ọ̀rẹ́ 2: 'Jọ́ 'kán pèlú! And another day too!

Ṣé dáadáa lọ wà? Are you well?

1: Daadaa ni, a yinLọ́un. We praise God, very well.

Tàbí ẹ kò gbọ́ pé a ti gbéyàwó ni? Or haven't you heard that we have got married?

2: Kí nla! Lóòótọ́? What? Is it true?

1: Bẹ́ẹ̀ ni, a ti ṣe ìnáwó ìyàwóò! Yes, we've run the expenses of marriage.

2: Ẹnikọ́ni kò bùn mi gbọ́ pẹ̀ẹ̀pẹ̀ẹ̀ (= rárá) No one informed me at all.

Áà! Ẹ kú ìnáwó ìyàwó. Greetings on the expenses of the marriage.

1: A dúpẹ́! Ìnáwó náà ni. Thank you. It was an expense.

2. Olúwa yíó ṣe ìyàwó ní oore. The Lord will be good to the bride.

1: Àmín o. Ire náà á kárí o! Amen. May the goodness go round (to all of us). (i.e., "And to you too!")

2: àmín. Olúwa yíó ṣe é ní abiamọn õ. The Lord will make her fruitful.

1: àmín o. Ẹ ṣe é. Thank you.

2: Olúwa yíó ṣe yín ní ọ̀rẹ́ araa yín o! The Lord will help you to enjoy mutual love and friendship.

1. Àmín o! Ẹ ṣe é, adùn á kárí. Thank you. Sweetness will go round (to all of us.)

6

Ọrẹ́ 2: Amín o! Ẹ kò ní rí ðòyà o! May you not find a comb (a divider, a separator) [ðóyà]

Ọrẹ́ 1: Amín o! Adùn náà á kárí o! May such pleasure be evenly distributed!

2: Amín.

15. Níná Ilé àwọn Ọlọ́mọ titun. At the House of a Family with a new Baby

Bàbá. Ọrẹ́è mi, ìyàwó bímọ lá`ná! My friend, (my) wife had a baby yesterday! [lá`ná]

Ìkíni: Áà! Bárìkà! Bárìkà! Congratulations! (May be repeated three times.)

Ẹ kú ewu ọmọ ō Greetings on (passing) the dangers of child birth!

Ìjẹ́ni: Òo, a dúpẹ́!

Ìkíni: Olúwa bá wa wo ọmọ náà! May the Lord help us to take care of this child!

Ẹ kú orí i re. Greetings for good luck!

Ìjẹ́ni: Amín! Ire á kárí o! Good luck to you too!

Ìkíni: Amín! Olúwa yíó`da sí `o! The Lord will spare him!

Ìjẹ́ni: Amín. Ẹ ṣe é, Amen! Thank you,

Olúwa ṣe èyin náà bẹ́ẹ̀! The Lord do the same for you.

Ìkíni: Amín! yíóò ní èrò lẹ́hìn `o! Amen! The child will have travelling-companions behind (him). (i.e. younger brothers and sisters.) [Intonation A at the beginning is emphatic.]

Ìjẹ́ni: Amín. Kò ní pọ̀ síbìí kan. May it not be unevenly balanced. ("It will not be (too) much in one place") (May all other people have such blessings too.) (Said by the parents.)

Ìkíni: Amín. Akọ mbábo? Male or females? (= Akọ tàbí abo?)

Ìjẹ́ni: Ọkùnrin ni! It is a boy.

Ìkíni: Ọlọ́run yíó ṣe é lọ́kùnrin jálẹ̀. God will make a real man of him all his life. [já, through, until/ilẹ̀, earth]

Ìjẹ́ni: Amín o. Ẹ kúu fífẹ́. Thank you for your love.

Ìjẹ́ni: Kí Olúwaá dá tiyín náà ní `o! — May the Lord spare your own!

(Ìbéèrè) — (Question)

Ìkíni: Orúkọ̀wo lẹ ha sọ ó? — What names have you given him?

(Answer)

Ìjẹ́ni: (Ìdáhùn) Sunday Abíọ́dún Babátúndé Òjó nil. — He is S.A.B. Òjó.

N.B. "Sunday" is the name given a male child born on Sunday. "Abíọ́dún", one born near a yearly festival; "Babátúndé," given to a boy born shortly after the death of his father or grand-father. ("Father has come again) "Òjó", the name given a child born with the umbilical cord round his neck.

Ìkíni: Olúwa jẹ́ ká mọ̀ ọ́n mọ orúkọ náà! — May the Lord let us know him (as we have) known those (famous) names!

Ìjẹ́ni: Àmín o. Ẹ dúró gba obì ọmọ ẽ — Wait for the child's kolanuts.

Ìkíni: Ẹ kú ìnáwó! Olúwa yíó `mú pòsè ohun tí ẹ ó fi tọ́júu rẹ̀! Kò ní tán níbẹ̀ o! — Greetings for money spent! The Lord will provide what you will need for his care. It will not finish there (i.e. in the store).

Ìjẹ́ni: Àmín o! Ẹ ṣe é o! A dúpẹ́ o! — Thank you!

Ìkíni: Àlejò tó wá di onílé, kú`bọ̀ o! — Visitor, who has come to be the owner of the house, Welcome!

Ayọ̀ abara tíntín! — Joy with a small body! (An idiom meaning "Good things come in small packages.")

Ìjẹ́ni: A dúpẹ́.

16. Nínú Ilé Olófò — At the house of the Bereaved

(Òfò is the death of a young person.)

Òré`kínní: Òrẹ́ẹ mi, ǹjẹ́ ẹ ti gbó pé òfọ̀ ṣẹ Òjó? — My friend, I wonder if you have heard that Òjó is bereaved.

Òrẹ́ kejì: Kí nla! N ò gbọ́ pẹ́ẹpẹ́ẹ! Ta ló ṣe aláìsí?

What!? I haven't heard at all. Who has died?

Òrẹ́ 1: Iyàwó rẹ̀ ló jáde láyé lá[illegible]! Láàárọ̀ `yí ni mo ṣẹ̀ṣẹ̀ gbọ́.

It is his wife who left the world yesterday. I have just heard this morning.

Òrẹ́ 2: Ó mà ṣe ō! Ẹ jẹ́ ká tètè lọ ò`hún.

What a pity! Let's go there quickly.

Òrẹ́ 1: Ó bíbéjì tán ló bí [illegible]kẹ́ẹ̀.

She died after having twins. [The falling tone on - kẹ́ẹ̀ shows emotion.]

Òrẹ́ 2: Áà! Ó mà ṣe ō! Olúwa fi mọ bẹ́ẹ̀!

What a pity! May the Lord put a stop to it! (i.e., not allow other deaths to occur.)

(They arrive at the house.)

Ìkíni: Ẹ pẹ̀lẹ́ o! Ẹ kú òfò o! — I salute you on the death of so young a person.

Ẹ kú ìrójú. — I salute you for bearing the loss with fortitude.

Ìjẹ́ni: Bẹ́a ti rii nìi ni. — That is how we saw the incident. [Ẹni èyí ni <èyí `un ni]

Ìkíni: Ó mà ṣe ō! Ẹ pẹ̀lẹ́! Ẹ pẹ̀lẹ́! Olúwa yíó tù yín nínú! — What a pity: I am sorry. The Lord will comfort you!

Ìjẹ́ni: Àmín! Hùùn! (A deep sigh.)

Ìkíni: Olúwa yíó rọ́ọ yín lójú. — The Lord will strengthen you.

Ìjẹ́ni: Àmín! Iná jó mi! — Fire has burned me. (It was a great blow to me.)

Ìkíni: Ẹ pẹ̀lẹ́! Olúwa yíó `dá àwọn ọmọọ rẹ̀ sí; a kò níí gbàgbé rẹ̀. — I am sorry. The Lord spare her children; may we not forget her!

Ìjẹ́ni: Àmín. A dúpẹ́, Ẹ ṣe ó. — Thank you.

Ìkíni: Áà! Igí mà dá o! Olúwa kò níí jẹ́ kí ó kú run. — A stick has broken! (What a sad thing!) The Lord will not allow her (line) to perish.

Ìjẹ́ni:	Àmín o! Ẹ ṣe é.	Thank you.
Ikíni:	Ẹ kú ọkàn. Ẹ jọ̀ọ́, ọkàn ni kí ẹ mú o!	We salute you for taking heart. Please take courage!
	Olúwa yíó`b´ wa tọ́jú àwọn ọmọọ rẹ̀.	The Lord will help us to take care of her children.
Ìjẹ́ni:	Àmín! A ó`ti ṣe ba ò mọ́kan?	Yes, what shall one do if one doesn't take heart? [ba < báa]
Ikíni:	Ẹ pẹ̀lẹ́! Olórun fòròn mọ́ bẹ́ẹ̀!	Sorry! The Lord limit the matter. [< kí Olórun kó fi òròn]
Ìjẹ́ni:	A dúpẹ́. Olúwa kò níí jẹ́ kí ẹ rí irúu rẹ̀ mọ́.	Thank you. The Lord will not let you see the like of it again!
Ìkíni-Ik:	Àmín. Olúwa yíó rẹ̀ yín lẹ́kún, yíó` fi àwọn ọmọọ rẹ̀ bùun yín	The Lord will dry your tears and will present her children to you.
Ìjẹ́ni:	Àmín. Ẹ kú ìdáròò mi.	Thank you for sympathizing with me.
Òrẹ́:	Ẹ jọ̀ọ́, à ń lọ.	Please, we are leaving.
Ìjẹ́ni:	Ẹ kú àsọ́ré wá--a-kìí sinni ō!	Thank you for coming. We don't escord people out (under such circumstances.)
Òrẹ́:	Ẹ ṣe é. Ẹ sá jó`kó.	Thank you. Just keep your seat.

17. Ní Ibi tí Òkú kú In a place where an old person has died

Òrẹ́ 1: Ẹ kú ìdájí o, òrẹ́ẹ̀ mi. Good morning, my friend. [ìdájí, early morning]

Òrẹ́ 2: Òo, ẹ kú ojúmọ́. Aláfíà kọ́ bí? Ẹ mà tètè jí! Thank you, good morning. How are you? You have certainly awakened early!

1. Aláfíà ni, a yinLọun. Bẹ́ẹ̀ ni, mo tètè jí! Mọ́júmọ́ àná ni bàbá Ògbẹ́ni "A" jáde lọ! Well, thank God. Yes, I have wakened early. Early yesterday morning Mr. A's father departed this world.

2: Ó mà ṣe ō! Síbẹ̀ náà, òkú ló kú òfò kọ́. I'm sorry to hear it! Still, the person who has died was not a young person.

Òrẹ́ 1: Ṣùgbọ́n arúgbó ẹni kì í súni. But one's aged relatives do not tire one (to the extent that one wants to get rid of them).

níbẹ̀ náà ni mò ń lọ bá`yí. That is where I am going now ("thus").

Òrẹ́ 2: Ẹ jẹ́ ká dìjọ ma lọ Let's go together. [ma < máa]

Ní ilé àwọn Oló`ṣú At the home of the bereaved people

Ìkíni 1 and 2: Ẹ pẹ̀lẹ́ o! We are sorry!

Ẹ kú ẹ̀hìn bàbá. We salute you, the survivors of (your) father! ("back of father")

Ẹ kú ìrójúu wọn! Olúwa jẹ́ kí ẹ̀hìn wọ́n dúró ō! We salute you for your fortitude over him! The Lord grant that his succession be good!

Ìjẹ́ni: Amín o! Ẹ kú àsáré wá. Thank you for coming so quickly. [sáré, run]

Ìkíni: Ẹ kú àṣẹ̀hìndè. I salute you on your bereavement. [àṣẹ̀hìndè < ṣe/ẹ̀hìn, back/dè, await]

Ìjẹ́ni: A dúpẹ́. Olúwa jẹ́ kí ọjọ́ irú bẹ́ẹ̀ẹ́ jìnnà sí araawọn. = Olúwa jọ́jọ́ọrú bẹ́ẹ̀ẹ́ jìnnà síra! May the Lord grant that such days be far apart!

Ìkíni: Àmín o. Olúwa kò ńíí jẹ́ kẹ̀hìn wọ́n bàjẹ́. The Lord will not let his departure be bad. (i.e., bring ill-luck to the family.)

Ìjẹ́ni: àmín. Ẹ kú ìdìde! Thanks for calling ("getting up").

Ẹ kú aájò èèyàn. Thanks for your fellow-feeling.

Ìkíni: Òo. A tún ń padà á bọ̀ láìpẹ́. We shall return soon. [á < wá]

Ìjẹ́ni: Ó daa. A kì í sinni ō. Ẹ wolẹ̀ ō! Good. One does not escort (a guest to the door, on such an occasion). Look at the ground! (You are welcome.)

Ìkíni: Òo. Ẹ jó`kó o! Olúwa yíó tìkùn ìbànújẹ́ o. Remain seated. The Lord will shut the door of sorrow.

Ìjẹ́ni: Àmín o.

Ìjẹ́ni 2: Òo, ó dígbà.

7. Ẹ jòó ẹ wọlé! Come right in, please! (60)

Ìkíni: Ẹ jòó, ẹ wọlẹ́ẹ̀! - ẹ wọlé wá!

Ìjẹ́ni: Ẹ ṣe é. Ẹ kú ìnáwó ilé `yí! I greet you for your expenses over the house.

Ìjẹ́ni 2: Òo, a dúpẹ́. Oore Ọlọ́run ni. Thanks, it is God's act of goodness.

Ẹ jòó ẹ jẹ́`kó lórí àga `yí. Please sit have your seat on this chair.

Ìjẹ́ni 3: A dúpẹ́. Thank you.

8. Ẹ kúùjọ̄`kó - ẹ kúùjọ̄òkó` = ẹ kú ìkàlẹ̀ - ẹ kúkàlẹ̀!
Greetings on being seated!

Ìjẹ́ni: A dúpẹ́. Ṣé daadaa ni mo bá a yín? Hope well it is I find you?

Ìjẹ́ni 2: Daadaa ni, ẹ ṣe é. Very well, thank you.

Ìkíni: Kàà sí ǹkan nílé? Hope there is nothing the matter at home?
[<kò ha; nílé]

Ìjẹ́ni: Kò sí ǹkan, daadaa la wà. There is nothing; we are fine. Or!

Kò sí nǹkankan lára ẹnikẹ́ni a yinLọ́un. Nothing is wrong with anybody, for which we praise God.

ìkíni: Ẹ kúkàlẹ̀! Greetings on being seated! [a repetition]

ìjẹ́ni: Òo, a dúpẹ́. Thank you.

9. Ẹ bá waa re· You find us well (Come to the table and eat with us.) Invite the visitor to the Table.

ìpè (invitation): Ẹ mọ́ rìn. Ẹ jọ́ẹ, ẹ bá waa re.

You have come at the appropriate time. Please come and eat with us. ("You know how to walk. Sit down, you find us well." An invitation to a senior person to join the group at the table.)

ìjẹ́ni: Ẹ ṣe é, yíó gbabii re. Thank you, it will go the right course. (i.e., the food will not go down the wind-pipe.)

= Ẹ ṣe é, mo ti ṣe bẹ́ẹ̀ ná. Thank you I have already done so.

= Ẹ ṣe é, arùn re yíó gbà á. Thank you, it will digest properly.

("The good worms will get it.")

18. Ní Ọjó Ìsinmi ku Àárọ̀ — On the Day before Sunday (Saturday)

Ìkíni: Ẹ kú Ìpalẹ̀mọ́n Ọ̀sẹ̀! — I greet you on your preparations for Sunday!

Ìjọ́ni: Òo. Olúwa jẹ́ kí ó bá wa láyọ̀! — May the Lord let it (the day) meet us joyfully! (May tomorrow morning be joyful.)

Ìkíni: Àmín o!

19. Ní Ọjó Ìsinmi — On Sunday

Ìkíni: Ẹ kú Ìsinmi òní o! — Greetings on Sunday!

Ìjọ́ni: Oo! Ẹ kú Ìsinmi náà. A ó ṣe ọ̀pọ̀ rẹ̀! — Sunday-greeting too! We shall (May we) celebrate many of them.

Ìkíni: Àmín o. Ṣọ́ọ̀ọ̀ì wo lẹ̀ ń lọ lónìí? — To what church do you go today = Where do you go to church today?

Ìjọ́ni: Ṣọ́ọ̀ọ̀ì Owódé ni Ìdáárọ̀ yí, ṣùgbọ́n ti Àláfíà-Olúwa ìrọ̀ ń lọ lálẹ́.

It is Owode Church this morning. But (the Church) of Àláfíà-Olúwa this evening.

Ìkíni: Ó dàbọ̀. Ti Ẹ̀ripa làwa ń lọ. — Goodbye, we are going to that of Ẹripa. (the one at Ẹripa)

Ìjọ́ni: Ó dara, ó dàbọ̀. Ẹ gbàdúrà fún wa ō! — All right, goodbye. Pray for us.

Ìkíni: Òo.

20. Ní Ọjó-Ìbí Ọ̀jó — On Ọ̀jó's birthday

Ìkíni: Iyá Ọ̀jó, ẹ kú ayọ̀ ọjọ́-ìbí o! — Mother-of-Ọ̀jó, greetings for the joy of the birthday! (i.e. that of her infant son.)

Ìjọ́ni: A dúpẹ́ o!

Ìkíni: A ó ṣe ọ̀pọ̀ rẹ̀ o! — Many happy returns of the day! ("We shall celebrate many of them!")

Ìjọ́ni: Àmín o. A ó ṣe tiyín o! — May we celebrate yours (too)!

Ìkíni: Àmín. A fẹ́ kọ orin fún Ọ̀jó. — We want to sing a song for Ọ̀jó.

Orin náà lọ bẹ́ẹ̀yí pé: — The song goes thus:

Ọjọ́ọ̀bí ayọ̀ fún o! — Happy birthday to you.

" " " " — " " " "

" " " ", Ọ̀jó — " " " ", dear Ọ̀jó.

A ó ṣe ọ̀pọ̀ọ̀ rẹ̀! — Happy birthday to you! (Many happy returns)

21. Ọdún Ajíńdé , tàbí Ìdúpẹ́ Ọdún, tàbí Ọdún Kérésìmesì, tàbí Ọdún Tituún kù sí dèdè. Easter, Thanksgiving, Christmas, or New Year is at hand.

Ìkíni: Ẹ kú Ìpalẹ̀mọ́ Ọdún o! — Greetings for your preparations for the festival! (Holy day, not holiday.) ("Holiday" is translated by "Ọjọ́....")

Ìjẹ́ni: Ẹ kú Ìpalẹ̀mọ́ náà. Olúwa jẹ́ kó bá wa láyọ̀. — Greetings likewise. God grant that it find us happy.

Ìjẹ́ni 2: Àmín. Olúwa jẹ́ kọ́dún náà bá wa láyé, kó bá wa láàyè, kó sì bá wa láyèe wa! — God grant that the Day find us on earth, alive and in our (proper) social place!

Ìjẹ́ni 3: Àmín o. Ẹ ṣe é. — Thank you.

22. Ní Ọjọ́ náà gan-an On the Day Itself.

(1) Lówúrọ̀ Ọjọ́ Ajíńdé. On Easter Morning (ajíńdé, resurrection)

Ìkíni: Ẹ kú ewu Ọdún Ajíńdé! — Greetings on (overcoming) the dangers (of the year preceding) the holy day of Easter.

Ìjẹ́ni: Ò o. Ẹ kú ọdún náà. Ẹ kú ìyèdún! — Greetings for the festival likewise. Greetings for living through the year (and seeing the new).

Ìjẹ́ni 2: Kí Olúwa jẹ́ kí Ọdún ya abo fún gbogboo wa ò! — May God grant that the year be a female year for all of us! (i.e., be a fruitful year.)

Ìjẹ́ni 3: Àmín o. A ó ṣe ọpọ̀ Ọdún o! — We shall celebrate many festivals (or, May we celebrate.)

(2) Ní Ọwúrọ̀ ọjọ́ Kérésìmesì Títí di Ọdún Titun. — From Christmas till New Year.

Ìkíni: Ẹ kú ewu Ọdún Kérésìmesì! — Greetings for (having survived) the dangers of the Christmas year! (Happy Christmas season)

Ìjẹ́ni: (as above.)

(3) Ní Ọwúrọ̀ Ọjọ́ Ọdún Titun, àti fún ọpọ̀lọpọ̀ ọsẹ̀ lẹ́hìn náà. — New year's Day, and for many weeks after.

Ìkíni: Ẹ kú ewu Ọdún Titun! — Greetings on the dangers of the New Year! (Happy New Year!)

Ìjẹ́ni: (as above).

23. Lénún Isé — At Work

Ìkíni: Ẹ kú iṣẹ́ = ẹ kúuṣẹ́ — Greetings for the work (that you are doing).

Ìjẹ́ni: Òo. Ẹ káàbọ̀ o! — Thank you. Welcome.

Ìkíni: Òo. Ẹ kú ìyàṇjú ńlá. — Thank you. Greetings for your effort.

Ìjẹ́ni: Òo. Iṣẹ́ ńdùn. — Thank you. The work is pleasant.

Tàbí — or

Ìkíni: Ẹ kú náyan. — Greetings for taking pains

= Ẹ kú wẹ́rẹ́wẹ́rẹ́. — Greetings on your meticulous care.

Tàbí — or

Ìkíni: Ẹ kú ìkúnpá. — Greetings on your hard work! ("armful")

24. Níníu Búkà Awunṣo (Ahunṣo) — At the Weavers' Workshop

Ìkíni: Ojú gbooro ō! — May the yarns and the spaces between them be steady! (ojú, eye; space)

Ìjẹ́ni: Ðàyà ó yà ō! Ẹ rè wá o! — And be evenly woven together. Come back again. ("May the comb comb it", i.e. push the wool down firmly.)

Ìjẹ́ni: Òo. Ẹ ṣé o! — Thank you.

25. Ní Àgbède — At the Blacksmith's Shop

Ìkíni: Àgbède Ògún, àrọ yè o! — Blacksmith of Ògún, may you forge and prosper! (N.B. Ògún is the Yoruba god of iron.)

Ìjẹ́ni: Àṣẹ! Ògún ó gbè yín o! = Ògún á gbè yín o! — Amen! Ògún will bless you!

Ẹ rè wá o! tàbí Ẹ káàbọ̀ ō! — Welcome.

Ìjẹ́ni 2: Òo. — Thank you.

26. Jíjáde lo sí Ojà — Going to the Market, setting out for Market

Ìkíni: Aré ilé, ọjà yá, ó dágbà ō! — People of the household, it's market time! Goodbye!

Ìjéni: Ẹ rè wá o! Ò dábò! Kẹ́ẹ́ mí ọmọ ọjà bò ō! — So long, now! We wish you successful bargaining. ("Bring back the daughter of Mother Market!")

Ìjéni 2: Òo.

Ìkíni: Ẹ má`pẹ́ o! — Don't be long.

Ìjéni: Òo.

27. Ní Ọjà — At the Market.

Ìkíni: Ẹ kú ọjà ō! — Greetings for being at the market.

Ìjéni: Òo, ẹ kábò! Tàbí Ẹ kú ọjà ná! — Welcome! or Greetings on the market indeed!

Àwọn tí ń ta nǹkan — Those who are selling things

Ìbéèrè: Ẹ jọ̀ọ́, níbo ni isò adìẹ? — (Question) Please, where is the chicken (-sellers') stall?

Ìdáhùn: Ẹ ká lọ! — (Answer) Come along! (A bit later)

Isò adìẹ niyí. — Here is the chicken-stall.

Ìkíni: Ẹ kúu títà ō! — Greetings to the seller!

Ìjéni: Òo, Ẹ kábò! Ẹ wá bá mi ra adìẹ àti ẹyindìẹ. — Thank you, welcome! Come buy a chicken and some eggs from me.

Ìbéèrè: Eé`ló ni adìẹ fumfun ńlá `yí? — How much is this big, white chicken?

Ìdáhùn: Àkùkọdìẹ ni. Ṣílè mé`wàá àábò ni. — It is a cock. It is five shillings, six pence.
[phonetically: Ṣílè márùn ńgbò ni]

Ìbéèrè: Àà! Ó wọ́n jù! Kò díín? — Oh, that is too dear. Won't you take anything less? ("Is it not less?" Prolonged vowel for question.)

Ìdáhùn: Eé`ló lẹ fẹ́ẹ́ san? — How much do you wish to pay?

Ìbéèrè: Ó wọ́n jù! Mo fẹ́ẹ́ san ṣílè mẹ́ta àábòọ.... — It is too dear! I wish to pay three shillings sixpence.
[The final rise to mid, ..-bòọ, is a bargaining intonation, meaning "Will you accept this?" A simple request for information, "Did you say 3/6d?" would be ṣílè mẹ́ta àábòọ?]

Ìdáhùn 2: Kò wọ́n juu...? Ó dara, ẹ sanwó. — It is not too costly. All right, pay me. [juu > jù, which falls after hightone > ju by tone compromise > juu..]

Ìbéèrè: Ṣílè mẹ́ta ńkó? What about three shillings?

Ìdáhùn: Kò gbà! Ẹ lè gbé e sílẹ̀. Not acceptable! You may put it down.

Ìbéèrè: Ajé o! I wish you financial success! (The keyword in the bargaining process.)

Ìdáhùn: Ẹ kówó rẹ wá. All right, bring your money! [wá is phonetically wàā, a grudging reply.]

Ìdáhùn: Ẹ gbà. Owó daadaa ni gbogboo rẹ̀. Take it. Every coin of it is good.

Ìkíni: Ẹ ó maa tà ō! May you continue to sell!

Ìjóni: Àmín o. Ẹ̀ ṣ ra ẹyin? Thank you. Won't you buy some eggs?

Ìjẹ́ni:2: Ẹ ṣe ó, a ní díẹ̀ lọ́wọ́. Thank you, we have some on hand.

28. Ẹ kúulé o! Greetings for being back Home.

Ìkíni: Ẹ kúulé o, arẹ́alé! Greetings, home-folks!

Ìjẹ́ni: Ẹ káàbọ̀! Ẹ kú ọjà. Welcome. Greetings on the market.

Ẹ ṣ mú ọmọ ọjà bọ̀ bí? You brought back Market's Daughter, didn't you?

Ìjẹ́ni:2: A dúpẹ́. Thank you.

Ìkíni: Ọjà o tẹ́ bí? The market was good, wasn't it?

Ìjẹ́ni: Ó daa ō. It was good.

Ìkíni: Òjó dà? Where is Òjó?

Ìjẹ́ni: Ó sun. He is asleep. [sun < sùun, with tone compromise. The rise to mid implies something else unspoken, such as: Ó sùn ni kò fi kíi yín < Ó sùn ni ìdí tí kò fi kíi yín. = Sísùn tó sùnni... etc. He is sleeping. That is why he didn't greet you.]

Ìkíni (another woman): Asùnwú o! May he sleep and grow! ("Act of sleeping and swelling!")

Ìjẹ́ni: Àmín o.

29. Ní Àkókò Òjò In the Rainy Season

Ìkíni: Ẹ kú òjò yí o! Greetings on this rainy season!

Ìjẹ́ni: A dúpẹ́. Òjò ni. Thank you. It is a (real) rain.

Ojò nítú tù wá lára. The rain is refreshing (to us).

Ìkíni: Kò ní ṣe wá lọ́ṣẹ́ o! May it not do harm to us!

Ìkíni: Kò ní ṣe wá lọ́ṣẹ́ o! May it not do harm to us!

Ìjẹ́ni: Àmín o!

30. Ní ìgbà ọ̀oru — At the Time of the Hot season (February - April)
(Or any hot spell)

Ìkíni:	Ẹ kú ooru `yí!	Greetings on the heat!
Ìjẹ́ni:	Coru ni! Kò níí ṣe wá lọ́ṣẹ́ o!	It is real heat! May it do us no harm!

31. Ẹni tí ó sín — One who Sneezes

(1) Ọmọndé tó sín:- — to a child who sneezes:-

Ìkíni:	Àsíntọ́, àsíngbó!	Sneezing for developing, sneezing for a ripe, old age!
Ìjẹ́ni:	Àmín o.	

(2) Àgbàlagbà — (an older person)

Ìkíni:	Bárìkà ō!	Welcome! (back to consciousness)
	tàbí	or
	Ẹ pẹ̀lẹ́ o!	Sorry!
Ìjẹ́ni:	A dúpẹ́.	Thank you.

32. Lílọ sí Ìrìn-àjò tàbí Ìdágbère — Going on a Journey

Ìdágbère — Saying goodbye to those at home.

Ìdá:	Ó dábọ̀ ẹ̀yin aráalé o!	Goodbye folks!
Ìkíni:	Ó dábọ̀ ō! Ó dígbà ō!	Goodbye! Until another time!
Ìjẹ́ni:	Ọ̀o. Ó dijọ́ `mí o!	Until another day!
Ìkíni:	Olúwa má kàtún rí o! = Olúwa má ṣe kọ àtúnrí araawa.	May the Lord not refuse our seeing each other again.
Ìjẹ́ni:	Àmín. Ó dìgbòó ṣe ō!	Until another time! [<di ìgbà tí ó]
Ìkíni:	Ọkọ̀ á rèfó o!	May the boat float! (May you not have a wreck.)
Ìjẹ́ni:	Àmín o.	
Ìkíni:	Ẹ jẹ́ kí maa gbú`róo yín o!	Let us hear from you! [<gbú`róo yín]
Ìjẹ́ni:	Ó daa. Ẹ kí Ọ̀jó bó bá ti oko dé o.	Greet Ọ̀jó when he is back from the farm.
Ìjẹ́ni 2:	Yíó gbọ́ .	He'll hear = We will.

33. Láti kí àwọn Olá (Oba, Baálè. etc.) — To Salute the Nobility, Kings, etc.

Ìkíni:	Kábíyèsí o!	Your Majesty!
	Kọ`mí Olá ó gùn!	May the life of the king be long!
	Kọọ pẹ́!	May you tarry (with us)!
	Kára ó le!	May your body be strong!

Ìjẹ́ni: (a courtier): Ó kí ọ! He greets you!

À lẹ ẹ kú! Greetings are being said to you. [à impersonal passive]

Ẹ maa wolẹ̀! Keep eyes on the ground! (i.e., "You are welcome!")

N.B. When the Ọba speaks and he is cheered, when he arrives and when he departs, you may hear:

Ìkíni: Káàbíyèsí! Aláyélúwà! Your Majesty, Lord of life and being.

34. Ẹni tí ó ṣe nǹkan dáradára someone who does something Exceptionally well.

Ìkíni: Sàdákétà! Gbẹ̀rè! Brave! Splendid!

Ìjẹ́ni: A dúpẹ́, Alàgbà! Thank you, Sir.

35. Ẹni tí ó ń ru Ẹrù One who is carrying a Load

Ìkíni: Ẹ kú ẹrù! Greetings on the load!

Ìjẹ́ni: Ò o. Ẹ kú ilé o! Greetings on your being at home!

tàbí

or

Ẹ kú `dúró! Greetings on standing!

tàbí

or

Ẹ ma ká lọ! Come along!

Ìkíni: Ò o. Ẹ káàbọ̀. Welcome

Ìjẹ́ni: Ò o. Ṣé daadaa la bá ilé? Do we find the house (family) well?

Ìjẹ́ni 2: Daadaa ni. Àdéé bá re ò! May the arrival home find good!

Ìjẹ́ni 3: Àmín o. Ẹ ṣe é! Sálùbáríkà! Thank you! Bless your heart!

36. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ Èèyàn ní ìjókó tàbí ìdúró Many persons sitting or standing conversing.

Ìkíni: Ẹ kú àpérò o! Greetings on your taking taking thought, taking counsel, conversing together.
= Ẹ kú ìníyàn!

Ìjẹ́ni: Ò o. Ẹ káàbọ̀ o! Ṣé ẹ ti dé lọ dó? Welcome, have you arrived well.

tàbí

or

Ò o, ẹ rè wá o! Thank you, welcome!

37. Àwọn tí Jàmbá ṣe Those involved in a Wreck

Ìkíni: Ẹ pọ̀lẹ́ o! Kìí ṣòro ò? I'm sorry. It isn't serious, is it?

Ṣe ẹnikẹ́ni kò fi ara pa o! I hope nobody was hurt!

Ìjẹ́ni: A dúpẹ́ o! Ọlọ́run kò jẹ́. Thank you. God did not permit (any injury).